# ÍKỌ̀SÍLẸ̀

Mary Owólabí

**ÍKỌSÍLẸ̀**
Láti ọwọ́ Diákónì Obìnrin Mary Owólabí
Copyright © 2017

**Àṣẹ tí a Kò fún ni.**

Pé a kò fún ẹnikẹ́ni láṣẹ láti tún kọ tàbí dàkọ apá kan nínú ìwé yìí ní ọ̀nàkọnà yálà nípa ẹ̀rọ ayárabíàṣá tàbí àwọn ọ̀nà mìíràn lái gba àṣẹ láti ọwọ́ ònkọ̀wé; àyàfi lílò fún bìí àkàjúwe tàbí àgbéyẹ̀wò tí ó ṣe kókó.

Gbogbo àkàjúwe ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tí a lò jẹ́ ti ìwé mímọ́ King James Version Bíbélì Mímọ́.

**Fún àdúrà àti ìmọ̀ràn, jọ̀wọ́ pe ònkọ̀wé:**
The Divine Message and Great Mission
Sórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ yìí:
+2348140606077; 07055512708

**Ẹ̀rọ ayárabíàṣá:**
thedivinemessageandgreatmissio@gmail.com

**ISBN:** 978-978-54106-6-2



# ÌPÈ ÌRÁNṢẸ́

Ẹni tí Ọlọ́run pè tí ó sì rán láti dín èrò ìjọba èṣù kù ní kíkọsílẹ̀ nípa ìtọ́ni àti ìfihàn àtọ̀runwá àti títọ́ sọ́nà nípa agbára Ẹ̀mí Mímọ́, láti tú àṣírí tí ó n darí ẹni sí ìsọdi ọ̀mìnira àti láti sìpẹ̀ fún àti láti gba àwọn ọmọ Ọlọ́run níyànjú ní gbogbo ayé, kí á ba le jèrè wọn padà sínú ìjọba Ọlọ́run tó ga jùlọ.

# ỌRỌ̀ ÀKỌ́SỌ

Ìkọ̀sílẹ̀ jẹ́ ohun ìríra sí Ọlọ́run, "Nítorí Olúwa, Ọlọ́run Ísráẹ́lì wípé, Òún kórìra ìkọ̀sílẹ̀: ẹnìkan fi ìwà ipá bo aṣọ rẹ̀ mọ́lẹ̀, li Olúwa àwọn ọmọ ogun wí: nítorí náà ẹ ṣọ́ ẹ̀mí yín, kí ẹ máṣe hùwà ẹ̀tàn." Mal. 2:16. Ó níhun ṣe pẹ̀lú rògbòdìyàn, nínú ayé àwọn olólùfẹ́, àwọn ọmọ wọn àti àwùjọ.

Ẹ̀mí búburú yìí ni ó wà nídì àwọn ìdílé tí ó pín, ìhùwà àìtọ́ wọn èwe/ọ̀dọ́, àgbèrè àti ọ̀pọ̀ àwọn ìwà búburú ní àwùjọ. Nítòótọ́, ẹnikẹ́ni kò lè gbèjà rẹ láì tako pípé ìfẹ́ Ọlọ́run fún "àjùmọ̀gbé àti ìdàpọ̀mọ́" ti ọkọ àti aya nínú ìgbéyàwó. Gen 2:24, Orin Dáfídi 45:10, 1Kor 7:10.

Èrò wípé kí á fi àyè gba ìkọ̀sílẹ̀ látàrí àìbáradọ́gba, àgbèrè àti àìlèkóraẹni ní ìjánu kìí ṣe èyí tí ó lọ́gbọ̀n; nítorí pé ó



lòdì sí ìlànà ti ìfẹ́ gẹ́gẹ́ bí a ti ti ọwọ́ Olúwa Jésù Krístì fi hàn.

"Ẹ̀yin ọkọ, ẹ fẹ́ràn àwọn aya yín, gẹ́gẹ́ bí Krístì sì ti fẹ́ràn ìjọ, tí ó sì fi ara rẹ̀ fún un; Kí òun kí ó lè sọ ọ́ di mímọ́ lẹ́yìn tí a ti fi ọ̀rọ̀ wẹ̀ ẹ́ mọ́ nínú agbada omi" Efésù 5:25-26.

Nínú ìwé yìí, a fún ìṣòro ìkọ̀sílẹ̀ ní ọ̀nà àbáyọ̀ ti ìwé mímọ́. Ìwọ yíò sì ka àwọn ìlànà tí a ti dánwò láti má jẹ̀ kí ìkọ̀sílẹ̀ kí ó wáyé nínú ìgbé ayé ìgbéyàwó rẹ, bí ìwọ bá tẹ̀lé ìfẹ́ Ọlọ́run fún ayé àti ìgbéyàwó rẹ.

Mo sọ nípa ìwé yìí gẹ́gẹ́bí àgbọdọ̀kà fún àwọn tí ó n wá ìfẹ́ àti ìdásí àtọ̀runwá nínú ìgbéyàwó wọn, pẹ̀lú ìnílọ́kàn láti má fi ààyè gba ìkọ̀sílẹ̀.

Ó jẹ́ àdúrà mi wípé Ọlọ́run ìfẹ́ yíò dá àláàfíà padà sínú àwọn ìgbéyàwó tí ó ti n ṣọ́nà ìkọ̀sílẹ̀. Rántí wípé Ọlọ́run kóríìrà ìkọ̀sílẹ̀.

**Olùṣọ́àgùntàn Isaac Gbádébọ̀ Fákúnlé.**
Alábojútó Pápá - Ìhìnrere ní North America ti Íjọ Àpóstélì Náà

# ÌFIJÌ

Mo fi ìwé yìí jì fún Ọlọ́run nípasẹ̀ Olúwa wa Jésù Krístì. Ọlọ́run alàáyè kanṣoṣo tí n gbani - ẹni tí kò gbà kí ẹ̀fúfù búburú ti ìpínyà kí ó gbá mi kúrò nínú ìgbéyàwó mi. Bàbá mi, O seun fún jíjẹ́ àṣírí, okun àti àṣeyọrí mi.



# ÌFÁÀRÀ

Ọ̀rọ̀ náà "ìkọ̀sílẹ̀" ti wọ́pọ̀ ní àyíká wa, kódà ní gbogbo àgbáyé. Láàrin àwọn Krístẹ́nì, kì í ṣe ohun tí ó yẹ kí á máa gbọ́ mọ́. Púpọ̀ nínú wa ti wá gbàgbọ́ wípé, a kò lè pa ara wa látàrí pé a fẹ́ mú ìdílé tàbí ìgbéyàwó wa kí ó dúró. Àwọn kan tilẹ̀ sọ wípé àwọ́n ti ṣe gbogbo ohun tí ó wà ní ìkáwọ́ wọn láti ri wípé ìgbéyàwó náà ṣàṣeyọrí síbẹ̀ síbẹ̀ kò ṣiṣẹ́; nítorí náà àwọn kò lè tẹ̀ síwájú pẹ̀lú rẹ.

Àwọn díẹ̀ nínú àwọn wọ̀nyí mọ̀ wípé, ìgbéyàwó wọn wà lábẹ́ ìdojúkọ ti ẹ̀mí láti ẹnu ọ̀nà ọ̀run àpáàdì, síbẹ̀ wọn kò lè borí tàbí sá àsálà kúrò nínú ìdojúkọ búburú náà. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn ti wá lùgbàdì ìdojúkọ yìí. Ìjì búburú

ìparun àti ìpínyà ti rí ààyè láti fẹ́ àti láti gbé ọ̀pọ̀lọpọ̀ wọn lọ ní abẹ́ àkóso èṣù.

Ìmísí ìwé yìí wá láti ọ̀dọ̀ Ẹ̀mí Mímọ́ láti jẹ́ kí á mọ̀ wípé, ìkọ̀sílẹ̀ mbẹ ní ààrin wa. Ohun tí ìjọ Ọlọ́run nṣe nípa rẹ̀, ohun tí a ní láti ṣe, àti pé kíni ìgbékalẹ̀ bíbélì fún wa láti jọba pẹ̀lú Olúwa wa Jésù Krístì lẹ́hìn ìrìn àjò wa nínú ayé yìí.

Mo gbàdúrà fún ore-ọ̀fẹ́ láti gbọ̀ ìkìlọ̀ yìí láti ọ̀dọ̀ ẹlẹ́dàá rẹ, kí èṣù má baà jà ọ́ lólè ohun ìní rẹ nínú ayé yìí àti ní ọ̀run. Àmín.



# TÁBÌLÌ ÀKÒRÍ


Ìpè Iránṣẹ́ ... ... ... ... iii

Ọ̀rọ̀ Àkọ́sọ ... ... ... ... iv

Ìfijì ... ... ... ... ... v-vi

Ìfáàrà ... ... ... ... vii-viii

Ìmọrírì ... ... ... ... x-xi

Ọ̀rọ̀ Ìsáájú ... ... ... ... xii - xiv

Ìtumọ Èdè ... ... ... ... xv-xvi

**ORÍ KÌN-ÍN-NÍ**
Ìgbékalẹ̀ Bíbélì Nípa Ìkọ̀sílẹ̀ ... 1 - 20

**ORÍ KEJÌ**
Àwọn Isẹ́ Ìjọ ... ... ... 21 - 24

**ORÍ KẸTA**
Àbá ... ... ... ... 25 - 42

**ORÍ KẸRIN**
Èrò Ìparí/Àkọtán ... ... 43 - 48

# ÌMỌRÍRÌ

Lákọ̀ọ́kọ́ jùlọ, mo fi ògo àti ọlánlá fún Ọlọ́run alàáyè kanṣoṣo nípasẹ̀ Olúwa wa Jésù Krístì fún jíjẹ́ àṣírí àti orísun ìmísí mi. Mo fi ìbùkún fún aṣẹ̀dá ọ̀run òun ayé tí ó mọ̀ mí láti inú ìyá mi wá, tí Ó sì ti pinnu rẹ̀ nípa ìpè àtọ̀runwá Rẹ̀ lórí ayé mi láti ní ipa lórí àwùjọ/ìran mi. Mo fi ìbùkún fún orúkọ mímọ́ Rẹ̀. Àmín.

Sí ọkọ mi ọ̀wọ́n, Alàgbà J.O. Owólabí fún jíjẹ́ ẹ̀yà ara ayé mi, fún níní ipa lórí ayé àti iṣẹ́ ìránṣẹ́ mi, fún jíjẹ́ ọkọ tí ó ṣọ̀wọ́n sí ògo Ọlọ́run. Mo sọ pé, mo dúpẹ́ mo sì nífẹ̀ ẹ́ yín gidi.

Sí àwọn ọmọ mi, fún jíjẹ́ ẹ̀yà ara iṣẹ́ ìránṣe mi àti fún ọjọ́ ọ̀la tí ó tàn nínú Krístì Jésù. Mo nífẹ̀ẹ́ yín ẹ̀yin ọmọ.



Sí ìyá tí ó bí mi lọ́mọ, Arábìnrin D.O. Adéwuyì Tóyè, obìnrin tí ó pé ojú ọ̀ṣùwọ̀n ni yín, ìyá tí ó lóye. Àdúrà ìgbàgbogbo àti ìpinu fún àlùyọ àti àṣeyọrí ní ìgbà ìṣòro àti ìdàámú nínú ìgbéyàwó yín ni Ọlọ́run rí tí ó sì fi ṣe mí ní ẹni tí mo jẹ́ lónìí. Ẹ gba àgbàyọrísíre àdúra ni. Ìyá mi, mo fi ọpẹ́ fún Ọlọ́run fún ore-ọ̀fẹ́ Rẹ̀ lórí ayé yín. Àdúrà mi nítòótọ́ fun yín ní pé èsù kò ní yọ̀ lórí ayé yín ní orúkọ nlá Jésù. Àmín.

Sí bàbá mi nínú Olúwa, Olùṣọ́àgùntàn I.G. Fákúnlé, Alábojútó Pápá - Ìhìnrere ní North America ti Íjọ Àpóstélì Náà, odún mẹ́ta dín díẹ̀ tí ẹ lò ní ìpínlẹ̀ Àbújá F.C.T láàrin oṣù kejìlá 2009 sí oṣù kẹjọ 2012, ní ipa nlá lórí ìgbé ayé ẹ̀mí mi àti ti iṣẹ́ ìránṣe mi. Bàbá, njẹ́ ẹ mọ̀ wípé iṣẹ́ ìránṣẹ́ yín ti mú ọ̀pọ̀lọpọ̀ akọni jáde fún ògo Ọlọ́run bí? Mo gbàdúrà pé ẹ ó gba adé ògo ní ìkẹhìn iré-ìje yín ní orúkọ nlá Jésù. Àmín.

Sí gbogbo ẹ̀yin tí Olúwa ti lò ní onírúurú ọnà, yálà nípa àdúrà, ọ̀rọ̀ ìyànjú, ìmóríyá, ìṣúná, ìdìdé àti àwọn ọ̀nà mìíràn. Mo gbàdúrà wípé ẹ kò ní ṣe é lásán ní orúkọ nlá Jésù. Àmin. Ẹ rántí wípé Òun kò pe ilé Jákọ́dù láti wá A lásán. Irúgbìn ìgbàgbọ́ yín yíò hù jáde dájúdájú ní orúkọ Jésù Krístì. Àmín.



# Ọ̀RỌ̀ ÌṢÁÁJÚ

Èṣù mọ wípé bí ẹnìkan ṣoṣo bá lé ẹgbẹ̀rún kan, ẹni méjì yíò lé ẹgbẹ̀wá. Nítorí náà, ó ti pinnu láti má jẹ̀ kí ẹni méjì ṣàṣeyọrí ní dídàpọ̀. Bí wọ́n bá sì ti dàpọ̀, ó ti pinnu rẹ̀ láti jà wọ́n lólè ayọ̀ àti ìṣọ̀kan tí wọ́n nílò láti jọ gbé gẹ́gẹ́bí ọkọ àti aya. Èṣù ẹni tí ó jẹ́ ọ̀tá ìdàpọ̀ wa, ti gbé àwọn ẹmẹ̀wà àti òun tìkararẹ̀ kalẹ̀ láti ri wípé kò sí ìṣọ̀kan ti ọkàn àti èròngbà láàrin lọ́ kọláya; nítorí ó mọ̀ pé nínú ìṣọ̀kan wọn ni ìṣubú òun wà. Ó sì mọ̀ pé àdúrà àgbàpọ̀ lọ́kọláya lágbára láti bi òun lulẹ̀ ní gbogbo ìgbà. Nítorí náà, ó máa n wà ní ìmúrasílẹ̀ láti ri pé iyè àwọn tọkọtaya tí afẹ́fẹ́ búburú ìpínyà ti fẹ́lù kò gba ìsíníyè, kí wọ́n má baà borí ìlàkàkà rẹ̀.

Ní àkókò òpin ayé yìí, èṣù ti gbé agbára wọ àwọn ẹmẹ̀wà rẹ̀ láti ṣe àwọn ojúṣe wọ̀nyí: nítorínáà, a ní láti pe òye wa sínú ewu tí ó wà nínú títẹ̀lé ẹ̀tàn ọ̀tá ọkàn wa nì (sàtánì). Nípa pé kí a kọ̀ láti jó sí ìlù ìtúká rẹ tí o nlù sí igbéyàwó wa.

Ọlọ́run ti ri wípé kò dára kí ọkùnrin máa dágbé, Ó sì ṣe olùrànlọ́wọ́ fún un, Gen 2:18. Ó ṣe pàtàkì fún wa láti mọ̀ wípé Ọlọ́run mọ̀ pé kò dára kí ọkùnrin máa dàgbé, èyí sì ni ìdí tí ó fi ṣe olùrànlọ́ wọ́ fún un. Ṣùgbọ́n nítorí èṣù n fẹ́ ìṣubú ọkùnrin, ó n gbìyànjú lati mú olùrànlọ́wọ́ (obìnrin) tí Ọlọ́run ti ṣètò fún ọkùnrin kúrò, kì oun (èṣù) ba lè ní ààyè àti pa ọkùnrin náà nípa ti ara àti ti ẹ̀mí. Kìí sì í ṣe ọkùnrin nìkan ni èṣù yíò parun, yíò pa obìnrin náà run pẹ̀lú; nítorí òun yíò rí ààyè láti tan obìnrin náà kúrò ní mímú ìdí tí a fi ṣẹ̀dá rẹ̀ ṣẹ.



# ÌTÚMỌ̀ ÀWỌN ÈDÈ

**Ìgbéyàwó:** Èyí ni ìdàpọ̀ láàrin ọkùnrin àti obìnrin. Ó jẹ́ àjọmọ̀ ọkùnrin àti obìnrin láti gbé pọ̀ ní gbogbo ọjọ̀ ayé wọn gẹ́gẹ́ bí ọkọ àti aya. Ọlọ́run ni ó ṣe ìgbékalẹ̀ ìgbéyàwó.

**Ìkọ̀sílẹ̀:** Èyí ni àìṣọ̀kan lọ́kọláya nínú ìgbéyàwó; ó jẹ́ àjọmọ̀ láàrin ọkọ àti aya láti má ṣe wà ní ìṣọ̀kan ọkàn àti èròngbà, ní ìlòdì sí ìgbékalẹ̀ Ọlọ́run. Ìkọ̀sílẹ̀ ni ọ̀nà tí èṣù ngbà láti ri wípé ọkùnrin àti obìnrin kò máa gbé ní ìbámu pẹ̀lú èròngbà Ọlọ́run fún ìṣèdá wọn.

Ó jẹ́ ọ̀nà ti àwọn lọ́kọláya fi máa nsọ fún ara wọn pé, àwọn kò lè gbépọ̀ bí ọ̀kan ṣoṣo. O jẹ́ ìfarahàn ìwà àti ìṣe àti má le

gbé pọ̀ bí ara kan gẹ́gẹ́bí Ọlọ́run ti da sílẹ̀; "àwọn méjì yíò dàpọ̀ wọn ó sì di ara kan."

Ìkọ̀sílẹ̀ sì tún jẹ́ iṣe tí o n sọ fún olùdásílẹ̀ ìgbéyàwó wípé kò ṣe dáradára. Àti wípé, ẹ̀yà igbéyàwó rẹ tí òun dàpọ̀ kò báramu. Ìṣe tí ó n ṣe àtúnṣe ohun tí ẹlẹ́dàá ọkàn rẹ ti ṣe télẹ̀, wípé ohun tí ó dá kò dára. Pàápàá nígbàtí bíbélì sọ wípé "ohun gbogbo tí ó dá, sì kíyèsí i, dáradára ni." Gen 1:31.

"Nwọ́n wọlé tọ Nóà lọ sí inú ọkọ̀ ní méjì méjì, àti akọ àti abo bí Ọlọ́run ti fi àṣẹ fún Nóà." Gẹn 7:9.



ORÍ KÌN-ÍN-NÍ

# IGBEKALE BIBELI NIPA IKOSILE

## ÌRẸ̀LẸ̀ LÁTI GBA Ọ̀RỌ̀ RẸ̀

Nítorí náà ẹ fi gbogbo èérí àti búburú aṣelékè lélẹ̀ lí apákan, kí ẹ sì fi ọkàn tútù gba ọ̀rọ̀ náà tí a gbìn, tí ó le gba ọkàn yín là." Jákọ́bù 1:21.

Ó ṣe pàtàkì, ó sì ṣe kókó fún wa láti mọ ohun tí bíbélì n sọ nípa ìkọ̀sílẹ̀ àti láti gba ọ̀rọ̀ Ọlọ́run náà, kí á má baà ṣì wá lọ́ nà nípa àwọn ìṣe ti ayé yìí àti ti èṣù pàápàá.

Ò n dá ara rẹ lárе nípa sísọ wí pé, Ọlọ́run kúkú mọ ọkàn rẹ, Ó sì mọ̀ wípé o ti ṣe ìwọ̀n tí o lè ṣe. O wípé Ó (Ọlọ́run) mọ̀ wípé o jẹ́ olódodo ní gbogbo ọ̀nà rẹ

àti pé ò n gbọ́ràn sí gbogbo òfin àti àṣẹ Rẹ̀: èyí ni mo ní láti sọ fún ọ ní ìbámu pẹ̀lú ọ̀rọ̀ Ọlọ́run.

“Nítorí ẹnikẹ́ni tí ó bá pa gbogbo òfin mọ́ tí ó sì rú ọ̀kan, ó jẹ̀bi gbogbo rẹ̀. 11 Nítorí ẹni tí ó wípé, máṣe ṣe àgbèrè, òun li ó sì wípé, máṣe pànìyàn. Njẹ́ bí ìwọ kò bá ṣàgbèrè, ṣùgbọ́n tí ìwọ́ pànìyàn, ìwọ́ di arúfin." Jákọ́bù 2:10-11. Bákannà, bí ìwọ kò bá pànìyàn ṣùgbọ́n tí o ṣe àgbèrè, ìwọ́ di arúfin. A gbọ́dọ̀ mọ̀ dájú wípé a kò ní ìdálàre kan ní yíyẹ̀ òfin, àṣẹ àti ìlànà Ọlọ́run sí ìbámu pẹ̀lú àwọn ohun tí à n kojú tàbí tí n ṣẹlẹ̀ láyé. Olọ́run ní ìgbekalẹ̀ tirẹ̀, àgbékalẹ̀ yìí kò sì ṣe é yí láti ba ìṣòro wa mu. Àwa ni a ní láti yí ara wa, àwọn ìdojúkọ wa, ipò àti àwọn ohun to yíi ká láti bá àgbékalẹ̀ Ọlọ́run mu.

Mo fẹ́ kí o mọ̀ wípé ìrẹ̀lẹ̀ láti gbọ́ àti láti gbọ́ràn sí ohun tí Ọlọ́run n fẹ́ láti ọ̀dọ̀ rẹ



jẹ́ ohun àmúlò fún ọ láti rìn wọ inú ore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run fún ayé rẹ. Bí o bá n gbéraga tí o sì ti sé ọkàn rẹ le láti má jọ̀wọ́ rẹ ẹ̀ sílẹ̀ fún àwọn àṣírí tí Ọlọ́run fẹ́ fi hàn fún ọ. Ìgbéraga ni à n pe èyí. Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run sọ nínú ìṣé Jákọ́bù 4:6 "Ṣùgbọ́n ó n fún ọ lí ore-ọ̀fẹ́ síi. Nítorí náà li ó ṣe wípé, Ọlọ́run kọ ojú ìjà sí àwọn agbéraga, ṣùgbọ́n ó fi ore-ọ̀fẹ́ fún àwọn onírẹ̀lẹ̀ ọkàn.”

Mo mọ̀ wípé lótìítọ́ ni o fẹ́ ní ìgbàlà: àwọn kan tí ó tilẹ̀ ní ìkọ́sílẹ̀ ní ìgbàlà, ṣùgbọ́n à n jà wọ́n lólè tàbí rẹ́ wọn jẹ níti ìbùkún ìdàpọ̀ eyí tí Ọlọ́run, olùdásílẹ̀ ìgbéyàwó, ti fi fún wọn. Ọ̀nà sí ayọ̀ èyí tí ò n fẹ́, wà nínú ìrẹ̀lẹ̀ rẹ sí ìdárí àti ìtọ́ni Ọlọ́run; nígbà náà ni òun yíò gbé ọ sókè nípa ti ẹ̀mí, ara àti ti ìgbéyàwó. "Ẹ rẹ ara yín sílẹ̀ níwájú Olúwa, òun ó sì gbe yín ga." Jákọ́bù 4:10.

**JẸ́ ẸNI TÍ Ó MÒYE OHUN PÚPỌ̀**

Rántí wípé "ohun ìjà wa kìí ṣe ti ara, ṣùgbọ́n ó lí agbára nínú Ọlọ́run láti wó ibi gíga palẹ̀; Àwá n sọ gbogbo èrò kalẹ̀, àti gbogbo ohun gíga tí n gbé ara rẹ̀ ga sí ìmọ̀ Ọlọ́run, àwá sì n di gbogbo èrò ní ìgbèkùn wa sí ìtẹríba fún Krístì." 2 Kor 10:4-5

Ìdí pàtàkì ní èyí tí a kò gbọdọ̀ fi wo ogun tí à n jà lọ́wọ́ pẹ̀lú ojú lásán. Kìí ṣe ojú lásán. Bíkòṣe ti ẹ̀mí ni, o sì ní láti mọ̀ wípé, o kò lè fi ohun ti ara wé ohun ti ẹ̀mí nínú irú nnkan báyìí. O gbọ́dọ̀ kojú rẹ nípa ti ẹ̀mí ní títẹ̀lé ètò ti Ọlọ́run fún ọ̀nà àbáyọ àtọ̀runwá.

Ẹ jẹ́ kí á wo irú ìṣẹ̀lẹ̀ yìí, bí ọ̀tá bá n lo ẹnìkejì rẹ láti mú ọ, tàbí o rí I pé ẹ̀mí búburú àti ẹ̀mí òkùnkùn mìíràn ti gbé ẹnìkejì rẹ wọ̀. Ní èyí tí ó jẹ́ wípé ó ti ta tàbí fi ẹ̀mí àti ayé rẹ̀ fún èṣù. Kíni ìwọ yíò ṣe ní irú ipò báyìí? Ṣe ìrántí pé ìfojúsùn èṣù ni láti tàn ọ́ kúrò, láti mú



kí o sọ ìfojúsùn rẹ nù, nípa bẹ́ẹ̀ kí o má ṣe bá Jésù jọba. Ó le è lo ẹnikẹ́ni, ṣùgbọ́n bí èṣù bá wá pinnu láti lo ẹnìkejì rẹ, njẹ́ ìwọ yó ha kọ ẹ̀yìn sí i nírú ipò yìí, kí o sì fi àyè gba ẹnìkejì rẹ láti parun sínú ibi bẹ́ẹ̀? Njẹ́ ìwọ yíò ma rò wípé 'ẹ̀bi rẹ̀ ni, jẹ́ kí ó kú sínú rẹ̀ nítorí pé òun ni ó yan ipa bẹ́ẹ̀'?

Rárá! Rárá!! Rárá!!! A kò ní láti fi irú ẹni bẹ́ẹ̀ sílẹ̀. Ojúṣe olólùfẹ́ ti krístẹ́nì ni láti di àmùrè kí ó sì gbàdúrà, nítorí ó ní láti rí ẹnìkejì rẹ̀ gẹ́gẹ́bí iṣẹ́ ìránṣẹ́ rẹ̀ àkọ́kọ́. N ò gbàgbọ́ pé agbára kan wà lábẹ́ ọ̀run tí kò ní foríbalẹ̀ nígbàtí a bá porúkọ Jésù ní òtítọ́.

Ìrírí yìí yíò fi kún ìmọ̀ rẹ nípa Ọlọ́run, yíò sì fà ọ́ sún mọ́ ẹlẹ́dàá rẹ si. Bí ó bá n dá orun mọ́jú tí o sì làkàkà ní gbígbàdúrà lóòrèkóòrè àti ní àìsinmi, ipá, agbára, okun, ore-ọ̀fẹ́ àti àwọn ẹ̀bùn ẹ̀mí mímọ́ ni a ó fi sínú ayé rẹ láti ṣe àṣeyọrí nlá

nínú ìgbéyàwó rẹ. O lè gba ayọ̀ tí ó tọ́ sí ìdílé rẹ padà. Èyí kìí ṣe ọ̀rọ̀ ẹnu lásán, mo lè sọ fún ọ wípé ó dájú!. O le è jẹ́ ohun èlò ní ọwọ́ Ọlọ́run láti jèrè ẹnìkejì rẹ padà sọ́dọ̀ Ọlọ́run àti sọ́dọ̀ ara rẹ; mó gbàdúrà pé Olúwa àwọn ọmọ ogun yíò ràn ọ́ lọ́wọ́ ní orúkọ nlá Jésù. Àmín.

**RỌ́JÚ**

Ìbùkún n bẹ fún ọ nígbàtí o bá fi sùúrù rọ́jú láti kojú ìdánwò àti ìdẹwò. Ìwọ yíò gba adé ìyè tí Ọlọ́run ti ṣèlérí fún àwọn tí ó fẹ́ Ẹ; kí o sì rántí wípé, nígbà tí a bá n dán ọ wò, máṣe sọ wípé "Ọlọ́run n dán mi wò" a kò lè dán Ọlọ́run wo láti ṣe ibi, Òun kìí sì dan ẹnikẹ́ni wò.

O gbọ́dọ̀ mọ̀ wípé ìdánwò má n wá láti ara àwọn ohun ìfẹ́kúfẹ̀ẹ́ èyí tí n wọ̀ wá lójú tí ó sì n fà wá lọ. Àwọn ohun tí a kúndùn wọ́nyí ni ó má n mú ni dẹ́ṣẹ̀. Nígbà tí a bá ti gbà ẹ̀ṣẹ̀ láàyè láti dàgbà, ó máa n bí ikú bí a ti fi àpẹẹre rẹ̀ hàn



nínú ìkọ́sílẹ̀ tí à n rí lónìí tí a sì n gbé pẹ̀lú. Jákọ́bù 1:12-15.

Bíbélì pọ́n ní dandan fún wa láti rọ́jú, láti máa ja títí a ó fi gba ìṣégun wa; èyí tí ó dájú nínú Krístì Jésù! Máṣe ṣe àìkàsí yìí pé o tilẹ̀ ti ṣìnu nígbàkan rí; o le tilẹ̀ ti tẹ̀lé àwọn ohun afẹ́ ayé èyí tí ó jásí ìrírí tí o ní lónìí. Ohun gbogbo wà ní ìkáwọ́ rẹ; o sì lè gba ẹnìkejì rẹ padà.

O má n sọ wípé, o ti gbìyànjú ṣùgbọ́n ẹnìkejì rẹ ni kò jẹ́ kí ìgbìyànjú rẹ kí ó yọ. Ó ṣe pàtàkì fún ọ láti mọ̀ ní ìkoríta yìí, ohun tí ó jẹ́ òtítọ́ pé, bí ìgbéyàwó rẹ kò bá tí i nì àṣeyọrí, ìwọ ni o fà á kìí ṣì í ṣe ẹnìkejì rẹ. Mo rọ̀ ọ́ pé kí o kọ́kọ́ ṣiṣẹ́ lórí ara rẹ pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ Ẹ̀mí Mímọ́ náà, ó dájú ìwọ yíò sì rí ìyípadà ní ṣíṣẹ̀ntẹ̀lé nínú ẹnìkejì rẹ. Mo gbàdúrà pé ìwọ yíò lè gba òtítọ́ yìí lónìí ní orúkọ nlá Jésù Krístì. Àmín. Bíbélì sọ nínú ìwé 1 Pet. 3:17 wípé, "Nítorí ó sàn, bí ó bá jẹ́ ìfẹ́

Ọlọ́run, kí ẹ jìyà fún rere iṣé ju fún búburú iṣé lọ." Ó sàn fún ọ láti jìyà fún ṣíṣe dídára ju kí o jìyà fún ibi ṣíṣe. Nítorínáà, è é ṣe tí o fi yan ìkọ̀sílẹ̀?

**JẸ́ ỌLỌGBỌ́N**

Gbọ́n ju àwọn ọ̀tá rẹ lọ. Mo gbàdúrà pé kí o gbà ore-ọ̀fẹ́ náà lónìí ní orúkọ nlá Jésù. Àmín. A kò gbọ́dọ̀ fi búburú san búburú, èébú fún èébú, àìṣòótọ́ fún àìṣòótọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. O kò gbọ́dọ̀ sọ wípé nítorí tí ẹnìkejì rẹ n yan àlè, ìwọ náà lè ṣe bẹ́ẹ̀. Rárá! O ní láti jẹ́ ọlọgbọ́n ju èṣù lọ, ẹni tí í ṣe olùdásílẹ̀ ìdàrúdàpọ̀ àti ìpínyà. Ó yẹ kí o kíyèsí pé àfojúsùn èṣù ni láti jà ọ́ lólè ìbùkún àti àyọ̀ ayé rẹ nínú ìgbéyàwó. Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run sọ wípé kí á má fi búburú sán búburú ni ó mú o yẹ láti jogún ìbùkún - 1 Pet 3:9. Krístì pàápàá, nígbàtí a fi ìwọ̀sí lọ̀ ọ́, òun kò da padà, kò tilẹ̀ lérí láti gbẹ̀san nígbàtí o n jìyà. Ó fi ọ̀rọ̀ náà lé Ọlọ́run lọ́wọ́, ẹni tí n dájọ́ òdodo. 1 Pet 2:23.



**MÁṢE GBẸ̀SAN**

Má ṣe gbẹ̀san ohun búburú tí ẹnìkejì rẹ bá ṣe, bí ó ti wù kí ó burú tó, fi ohun gbogbo lé Ọlọ́run lọ́wọ́. Òun tí ó dá ìgbéyàwó náà yíò wá ẹ̀yà tí ó sọnú, yíò sì yanjú ohun gbogbo nígbàtí a bá fi lée lọ́ wọ́ pẹ̀lú ìrẹ̀lẹ̀. Bíbélì sọ wípé ti Ọlọ́run ni ẹ̀san. Romu 12:19.

O ti pinnu nínú ọkàn rẹ̀ láti máṣe tẹ̀lé ìlànà Ọlọ́run lórí ohun tó n ṣẹlẹ̀ náà; o lérò wípé Ọlọ́run kò mọ ohun tí ò n là kọjá. O sì n wípé ìrírí rẹ yàtọ̀ sí ti àwọn tí bíbélì báwí. Ò n rí ara rẹ bí èyí tí o dá yàtọ̀, nítorí náà, o yọ ara rẹ kúrò nínú àwọn tí n tẹ̀lé ìlànà Ọlọ́run lórí irú ohun bẹ́ẹ̀.

O tilè n sọ wípé rárá, ìwọ kìí ṣe ángẹ́lì nítorí náà kí Ọlọ́run máṣe ni lérò pé ìwọ́ yíò jẹ́ pípé. Hún hùn! Ò n fi ọ̀run àpáàdì ṣeré. òtítọ́ ni pé ọ̀run àpáàdì wà. Òtítọ́ ni ọ̀rẹ́. Mo lérò wípé ó jẹ́ ohun ọlọgbọ́n

fún ọ láti jìyà báyìí, kí o sì jà fún ìgbéyàwó rẹ. Máṣe jẹ́ kí èṣù lo pánpẹ́ rẹ̀ láti rán ọ lọ sí ọ̀run àpáàdì nípa jíjẹ́ iṣẹ́ fún ọkàn rẹ láti gbẹ̀san ohun gbogbo tí ẹnìkejì rẹ ti ṣe sí ọ. ṢỌ́RA!

**KÒ SÍ ÌPÍNYÀ**

Kódà àwọn Farisí bi Jésù léèrè bí a bá gba ọkùnrin láàyè láti kọ aya rẹ̀ sílẹ̀ fún ìdí yòówù. Jésù sì dá wọn lóhùn pẹ̀lú ọ̀rọ̀ Ọlọ́run, ìwé mímọ́, tí sọ "RÁRÁ SÍ ÌKỌ̀SÍLẸ̀" tí ó sì fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ wípé ní ìbẹ̀rẹ̀, Ọlọ́run dá wọn takọtabo. Èyí ni ó ṣàlàyé bí ọkùnrin ti ṣe fi bàbá àti ìyá rẹ̀ sílẹ̀ tí ó sì dàpọ̀ pẹ̀lú aya rẹ̀, tí àwọn méjèèjì sì di ara kan. Jésù wípé níwọ̀n ìgbà tí wọn kìí ṣe méjì mọ́ kí ẹnikẹ́ni, ìṣòro kíṣòro, ohun yòówú, ìwàkíwà, agbára k'ágbára, ipá k'ípá, olùṣọ́-àgùntàn k'ólùṣọ́-àgùntàn, òbí k'òbí, ọ̀rẹ́ k'ọ̀rẹ́, àbúrò k'àbúrò, ọmọkọ́mọ, tàbí ohunkóhun kí ó ya ohun tí Ọlọ́run ti sopọ̀ ṣọ̀kan. Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run sọ wípé KÍ



ẸNIKẸ́NI... Èyí túmọ̀ sí wípé, ohunkohun kò gbọdọ̀ pín ẹ̀yin méjèèjì níyà. Àgbékalẹ̀ bíbélì ní èyí. A kò lè yí i padà, yẹ̀ ẹ́ tàbí kí á tun ṣe láti bá ohun tó n ṣẹlẹ̀ sí ọ mu. Ìwọ ni o ní láti yípadà kí o sì wà ní ìbámu pẹ̀lú ìfẹ́ Ọlọ́run fún ayé rẹ. Mo gbàdúrà pé, ore-ọ̀fẹ́ yìí kí ó jẹ́ tìrẹ báyìí ní orukọ Jésù.Àmín.

Ní iwájú Ọlọ́run Ẹlẹ́dàá rẹ, èyin méjèèjì jẹ́ ọ̀kan ṣoṣo. Nígbàkúgbà tí ó bá rí ọ ó gbàgbọ́ wípé òún ti rí ẹnìkejì rẹ nítorí pé ẹ̀yin méjèèjì jẹ́ ara kan.

Mo mọ̀ wípé ìwọ náà, bí àwọn Farisí ìgba nì, n béèrè ìdí tí Mósè fi sọ nínú òfin wípé ọkùnrin lè fún aya rẹ̀ ní ìwé ìkọ̀sílẹ̀ kí ó sì kọ̀ ọ́. Mo sọ fún ọ báyìí, pàápàá bí Krístì ti so fún wọn nígbà nì pé, Mósè gba ìkọ̀sílẹ̀ láàyè nítorí àyà líle wọn. Bíbélì wípé èyí kìí ṣe àròtẹ́lẹ̀ Ọlọ́run; èyí túmọ̀ sí pé àṣẹ àti àgbékalẹ̀ Ọlọ́run ni wípé kò sí ìkọ̀sílẹ̀. Mósè, tí i ṣe

ẹlẹ́ran ara bí ìwọ àti èmi, sọ wípé, ó dára, bí ọkàn rẹ bá ti sé le, tí o kọ̀ láti gbọ́ràn sí ohun tí Ẹlẹ́dàá rẹ ti paláṣe fún ọ, nígbànáà ni o leè fi aya rẹ sílẹ̀ bí ó bá ṣe àgbèrè; bẹ́ẹ̀ ni ó sì gbé 'àmọ́' le fún wọn pé ó pọn dandan fún wọn láti mọ̀ pé, ẹnikẹ́ni tí ó bá fẹ́ aya tí a kọ̀ sílẹ̀ ti mú kí ó ṣe àgbèrè.

Mo fẹ́ kí o mọ̀ ní ìkoríta yìí pé, bí o bá kọ ẹnìkejì rẹ sílẹ̀ tí ẹlòmíràn sì fẹ́ ẹ, kìí ṣe ẹnìkẹta (ẹni tí ó fẹ́ ẹ) nìkan ni ó ti jẹ́ kí ó ṣe àgbèrè ṣùgbọ́n o ti mu ẹnìkejì rẹ̀ ṣe àgbèrè pẹ̀lú.

Mo gbàdúra pé agbára Ọlọ́run ní orúkọ Jésù Krístì yíò yọ́ ọkàn rẹ tí ó le nì láti gba òtítọ́ ọ̀rọ̀ Ọlọ́run ní orúkọ nlá Jésù. Àmín.

Njẹ́ ìwọ́ mọ̀ pé bíbélì sọ wípé, ó sàn fún ọ láti má ṣe ìgbéyàwó rárá jú pé kí ó gbéyàwó kí o sì yan ìkọ̀sílẹ̀. Nítorí náà, bíbélì kò fi ìkọ̀sílẹ̀ fún wa bí ohun tí a le



yàn. Ohun tí a le yàn ni pé, kí o máṣe gbéyàwó rárá, bí o ò bá le fi àkókòò àti òminira rẹ sin Ọlọ́run; bí o bá sì ti gbéyàwó, o ní láti mọ̀ wípé títí ikú yíò fi yà yín ni. O leè yàn láti má gbéyàwó, bí a bá fún ọ ní ore-ọ̀fẹ́ láti jẹ́ olótìítọ́ sì i. Ṣùgbọ́n níwọ̀n ìgbà tí o ti gbéyàwó, ààyè kò sí ní ọ̀nà tí bbélì fún ọ láti fi ẹnìkejì rẹ sílẹ̀ fún ìdí yòówù. Mat 19:3-12.

"A fi òfin de obìnrin níwọ̀n ìgbà tí ọkọ rẹ̀ bá wà láàyè; " 1Kor 7:39.

Níwọ̀n ìgbà tí ó wà láàyè, o kò lè fẹ́ elòmíràn ni ọ̀rọ̀ Ọlọ́run wí. Èyí ni ìfẹ́ Ọlọ́run fún ọ. Páùlù àpóstélì ínú 1Kor 7:10:11 sọ wípé "ṣùgbọ́n àwọn tí ó ti gbéyàwó ni mo sì pàṣẹ fún, ṣùgbọ́n kìí ṣe èmi, bíkòṣe Olúwa, kí aya má ṣe fi ọkọ rẹ̀ sílẹ̀: ṣùgbọ́n bí ó bá sì fi í sílẹ̀ kí ó wà lí àìlọ́kọ, tàbí kí ó bá ọkọ rẹ̀ làjà: kí ọkọ kí ó máṣe kọ aya rẹ̀ sílẹ̀." Ẹ̀yin méjèèjì gbọ́dọ̀ máa gbé papọ̀ nínú ààyè yòówù tí Olúwa ti fi yín sí.

## ẸWÀ RẸ

Ó yẹ kí o fiyèsí báyìí pé ohun tí ó mú ọ rẹwà gẹ́gẹ́bí onígbàgbọ́ ni ìgbọ́ràn rẹ sí ìfẹ́ àti àṣẹ Ọlọ́run. Ẹwà rẹ yálà bí ọkùnrin tàbí obìnrin, kò yẹ kí ó jẹ́ ti ẹ̀ṣọ́ òde tàbí nípa ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ tí n sọ ti ìmọtaraẹni nìkan, bíkòṣe kí o wọ ara rẹ ní ẹwà àtinúwá; ní ṣíṣe pípé ìfẹ́ Ọlọ́run àti gbígbọ́ràn sí àṣẹ rẹ̀, ẹwà tí ẹ̀mí tí ó n ṣe pẹ̀lẹ́ tí ó sì dákẹ́ rọ́rọ́, èyí tí kìí sá, tí ó ṣe iyebíye sí Ọlọ́run. Àwọn ẹni mímọ́ ìgbàanì ṣe ara wọn lẹ́wà nípa gbígbẹ́kẹ̀lé Ọlọ́run àti gbígba ìṣàkóso rẹ̀. 1 Pet 3:3-4

Bíbélì sọ nínú 2 Pet 2:21 wípé, yíò san bí o kò bá mọ ọ̀nà òdodo ju pé kí o mọ̀ ọ́, kí o sì kọ̀ àṣẹ tí a ti fi fún ọ sílẹ̀ láti gbé ìgbé ayé mímọ́. Ohun pàtó tí bíbélì n sọ ni pé, ò n ṣe bí ajá tó padà síbi èébì rẹ̀ àti bí ẹlẹ́dẹ̀ tí ó padà sí inú ẹrọ̀fọ̀. Ó jẹ́ ohun ìtìjú.

Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run nfi àìgba ìfẹ́ àti àṣẹ Ọlọ́run sínú ayé rẹ nípa ti ìgbéyàwọ́ rẹ wé ajá



àti ẹlẹ́dẹ̀. Mo gbàdúrà pé, ẹ̀mí ajá àti ẹlẹ́dẹ̀ tí ọ̀tá ọkàn rẹ n lò ní àyíká rẹ báyìí bí ìkuúkú túká báyìí ní orúkọ Jésù. Àmín.

## ÌTỌ́NI

Ò n ronú bí o ó ti ṣe, o kò tilẹ̀ mọ ibi tí o ó ti bẹ̀rẹ̀, ò n bi ara rẹ léèrè èyí tí o ó kọ́kọ́ ṣe. Mo wí fún ọ, gbogbo ohun tí o nílò ni kí o rẹ ara rẹ sílẹ̀ pátápátá láti le dúró de Ọlọ́run fún ìdarí. Òun yíò darí rẹ, yíò sì fi ọ́ m'ọ̀nà. Ó ṣetán nígbàkúgbà láti fún ọ ní ọgbọ́n àti ìmọ̀ tí o nílò láti mú ẹnìkejì rẹ padà sọ́dọ̀ rẹ̀.

“Bí ó bá ku ọgbọ́n fún ẹnikẹ́ni, kí ó béèrè lọ́wọ́ Ọlọ́run, ẹni tí í fi fún gbogbo ènìyàn ní ọ̀pọ̀lọpọ̀, tí kì í sì bá ni wí, a ó sì fi fún un." Jákọ́bù 1:5.

Bíbélì pọ́n ní dandan fún wa láti béèrè lọ́wọ́ Ọlọ́run tí n fi fún ni lọ́pọ̀lọpọ̀, Òun yíò sì fi fún wa. Òun kì yíò bá ọ wí fún

bíbéèrè. Ṣùgbọ́n nígbàtí ìwọ bá béèrè lọ́ wọ́ rẹ̀, ri dájú wípé ìgbàgbọ́ rẹ wà nínú Ọlọ́run nìkan. Má ṣiyèméjì, nítorí pé ẹni tí ó bá n ṣiyèméjì dàbí ìgbì omi òkun tí afẹ́fẹ́ n fẹ́ tí n bì síwá bì sẹ́yìn. Gbẹ́kẹ̀lé E láti darí re, Òun yíò ṣe é; Ó jù bẹ́ẹ̀ lọ láti darí àti láti fi ọ́ mọ̀nà tí ó tọ́.

**Ọ́BÁ ÀWỌN ÒFIN**

"...ìwọ fẹ́ ọmọnìkejì rẹ bí ara rẹ." Gal. 5:14b. O ní láti fẹ́ ọmọnìkejì rẹ bí o ṣe fẹ́ràn ara rẹ. O ní láti fẹ́ràn ẹnìkejì rẹ bí o ti fẹ́ràn ara rẹ, nítorí pé ó jẹ́ ẹ̀yà ara rẹ. Ẹnìkejì rẹ tilẹ̀ ju ọmọnìkejì rẹ lọ, ẹnìkejì rẹ jẹ́ íwọ tìkalára rẹ. Bí ó bá fẹ́ràn rẹ̀ dójú àmì, o kò ní ronú ìkọ̀sílẹ̀ fún ìdíkídìí. Òfin ni, bẹ́ẹ̀ àṣẹ sì ni, o gbọ́dọ̀ fẹ́ràn ẹnìkejì rẹ bí ara rẹ - njẹ́ o ta ara rẹ tàbí o sọ ara rẹ nù nígbàtí o bá ṣe àwọn ohun tí ìwọ tìkalára rẹ kò lè gbàgbọ́ pé o leè ṣe bí? Rárá, o kò ṣe é! Èéṣe tí o fi rí ìkọ̀sílẹ̀ tàbí ìpínyà gẹ́gẹ́bí ohun tí o yàn? Kì í ṣe ohun tí o le yàn, kò sì rí bẹ́ẹ̀.



O gbọ́dọ̀ fiyèsi pé, bí o bá pa gbogbo òfin àti àṣẹ Ọlọ́run mọ́ ku ẹ̀yọ̀ kan, níṣe ni ó dàbí ẹni pé o kò pa nkankan mọ́. Nítorí náà, o ní láti gba ẹnìkejì rẹ gẹ́gẹ́bí ó ti rí (Jákọ́bù 2:8-10). Nípa bẹ́ẹ̀, ò n pa àṣẹ Ọlọ́run mọ́. O gbọ́dọ̀ gbáradì, kí o sì dúró ṣinṣin nínú ìgbàgbọ́, kí o ní ìgboyà, kí o jẹ́ alágbára, kí o sì ṣe ohun gbogbo pẹ̀lú ìfẹ́. O gbọ́dọ̀ pinu láti padà fẹ́ràn ẹnìkejì rẹ: ó jẹ́ ìpinu tí o gbọ́dọ̀ ṣe báyìí. Yàn láti gbé ìgbé ayé ọmọnìkejì rẹ kí o sì di ẹni ìgbàlà tàbí kí o yan ọ̀nà àbáyọ mìíràn (ìkọ̀sílẹ̀) kí o sì di ẹni ìparun (ikú) - ikú ayérayé.

**GBÀDÚRÀ FÚN ẸNÌKEJÌ RẸ/ẸNÌKEJÌ RẸ TÍ O KỌ̀ SÍLẸ̀. Matt. 5:46-47**

O ní láti gbàdúrà fún àwọn tí n ṣe inúnibíni sí ọ. Kódà kí ẹnìkejì rẹ burú jáì, tó bẹ́ẹ̀ tí ó sì ti fi ààyè gba èṣù láti wọnú ẹbí rẹ, o ní láti sa gbogbo ipá rẹ láti dáríjì í, bá a làjà, kí ò sí mú àjọṣepọ̀ yín padà bọ̀ sípò. Ojúṣe rẹ ni láti gbàdúrà fún ẹnìkejì rẹ. Ìlàjà náà gbọ́dọ̀

wáyé báyìí, kódà kí o ti fún un ní ìwè ìkọ̀sílẹ̀. Nípa gbígbàdúrà fún ẹnìkejì rẹ pàápàá ní àkókò ìrújú yìí, o lè borí búburú pẹ̀lú rere. Jésù wípé a ní láti fẹ́ràn àwọn ọ̀tá wa. Bí o bá fẹ́ràn ọ̀tá rẹ ni (ẹnìkejì rẹ/ẹni tí o kọ̀sílẹ̀) tí o sì ṣe dáradára si, o ó fihàn lótìítọ́ pé Jésù ni Olúwa ayé rẹ. Èyí ṣe é ṣe fún kìkì àwọn tí ó fi ara wọn fún Ọlọ́run ní kíkún nìkan nítorí pé Òun nìkan ni ó le gbà ọ́ lọ́wọ́ ìmọtaraẹni nìkan.

Ní àkókò yìí, o ní láti wá kí o sì fọkàn tán agbára Ẹ̀mí Mímọ́ láti ràn ọ lọ́wọ́ láti fẹ́ràn ẹnìkejì rẹ padà. Láti bá ọ dá ìfẹ́ tí o ní s ẹnìkejì rẹ padà, èyí tí èṣù ọ̀tá ayé rẹ, àyọ àti ìdàpọ̀ rẹ tí já ní ṣíṣẹ̀ntẹ̀lé gbà nínú ọkàn rẹ padà.

O ní láti mọ̀ wípé ó jẹ́ ohun tí ó ṣeéṣe kí ìfẹ́ náà padà sínú ọkàn rẹ àti sí ọkàn ẹnìkejì rẹ. Dán an wò lónìí kí o sì rí ìyanu tí ó wà nínú ìfihàn àtọ̀runwá yìí nípa agbára Ẹ̀mí Mímọ́ fún ayé rẹ.



Ó dámilójú pé ọ̀rọ̀ ẹ̀rí rẹ n bọ̀ bí o bá ti ṣe gba ìfẹ́ àti èrò Ẹlẹ́dàá rẹ fún ayé rẹ.

Bíbélì wípé, bí o bá fẹ́ràn ẹnìkejì rẹ kìkì nígbàtí òún bá fẹ́ràn rẹ, kíni o ti ṣe yàtọ̀ sí aláìgbàgbọ̀ àti pé èrè wo ni ìwọ́ ní? Bí o bá ṣe dáradára sí ẹnìkejì rẹ nígbàtí ó bá n fẹ́ ọ tí ó sì n kẹ́ ọ, kíni o fi yàtọ̀ sí ẹlòmíràn? O ni láti dàbí Jésù nínú ìhùwàsí, nínú ìwà mímọ́, ní ìṣe, ní gbígbé ìgbésẹ̀, ní dídàgbà àti ní ìfẹ́. Kí o wá láti fẹ́ràn ẹnìkejì rẹ ní pípé bí Ọlọ́run ti fẹ́ràn wa. (Matt. 5:44b-47).

## JÍJÌYÀ PẸ̀LÚ KRÍSTÌ JESÙ

Ó ṣe pàtàkì láti fiyèsí ibí yìí pe a kò kàn fún ọ ní ànfàní látí gbọ́kàn lé e nìkan bíkòṣe láti jìyà pẹ̀lú rẹ̀. Nínú ìjìyà rẹ pẹ̀lú rẹ̀, ni a n mú ọkàn wa kúrò nínú ìrọ̀rùn tó jẹ́ ti ayé. Ó n mú àwọn onígbàgbọ́ tí kò fi ẹsẹ̀ múlẹ̀ kúrò. Ó n fi okun kún ìgbàgbọ́ àwọn tí n rọ́jú. Yíò sì jẹ́ àpẹẹrẹ fún àwọn èlòmíràn tí yíò tẹ̀lé ọ. Nígbàtí a bá jìyà fún ìgbàgbọ́ wa, kò

túmọ̀ sí wípé a ti ṣe ohun kan lòdì, ṣùgbọ́n ní ọ̀pọ̀ ìgbà, ìdàkejì ni ọ̀rọ̀ náà. Yíò sì fi hàn pé a jẹ́ olódodo. Jíjìyà pẹ̀lú Krístì ni yíò tún ìwà rẹ mọ. Fílípì 1:29.

O ní láti mọ̀ pẹ̀lú wípé ìjìyà rẹ pẹ̀lú Olúwa Jésù Krístì yíò mú ọ dáriji ẹnìkejì rẹ kí ó sì kọ̀ láti fi ààyè sílẹ̀ fún ìkùnà ara yín. Kol 3:2-16.



ORÍ KEJÌ

# ÀWỌN IṢẸ́ ÌJỌ

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìjọ ti gbà kí àwọn lọ́ kọ̀láya tí ó ti kọrasílẹ̀ kí wọ́n tún ìgbéyàwó ṣe lábẹ́lẹ̀; wọ́n n dára wọn láre wípé ó ti ṣẹlẹ̀ láti ọjọ́ pípẹ́. Wọ́n wípé ẹni náà ti gbìyànjú tó. Wọn kò mọ̀ pé àwọn tí n fi ọgbọ́n yẹ àgbékalẹ̀ ti ọ̀run láti bá ohun tó n ṣẹlẹ̀ sí wọn mu ni. Wọ́n sọ pé ó yé Ọlọ́run bí ọ̀rọ̀ náà ti rí. Wọ́n ti gbe gbági.

Àwọn olórí ìjọ kọ̀ọ̀kan pàápàá tilẹ̀ dásí àwọn ọ̀rọ̀ ìdílé tí ó ti dàrú àti ti ìkọ̀sílẹ̀. Àwọn kan wà tí wọ́n ti wà lẹ́nu àtúnto rẹ̀ fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ oṣù àti odún tí kò sì ní àṣeyọrí. Wọn yíò wá gba abẹ́nú yanjú rẹ̀ sí pé ọkùnrin tàbí obìnrin náà ti ní òmìnira láti lọ tún ìgbéyàwó ṣe, nítorí

lójú tiwọn gbogbo ipá ni wọ́n ti sà. Ohun tí n kò lè sọ ni pé, mélòó nínú àwọn wọ̀nyí àti àwọn èyìyàn Ọlọ́run bẹ́ẹ̀ ni wọ́n ti fi àkókò wọn sílẹ̀ láti gba àdúrà ìṣìpẹ̀ lórí àwọn lọ́kọláya tí ó pínyà wọ̀nyí? Mélòó? Afàdúràjagun mélòó ni a tilẹ̀ ní? Àwọn ìránṣẹ́ Ọlọ́run mélòó ni wọ́n tilẹ̀ yẹ níwájú Ọlọ́run láti jẹ́ agbàdúrà ìṣìpẹ̀? Kíni ohun tí ọkàn àwọn ìránṣẹ́ Ọlọ́run wọ̀nyí n sọ? Àní, báwo ni ọkàn rẹ ti rí níwájú Ọlọ́run, Ẹni tí o rí gbogbo ọkàn? Njẹ́ irú ẹni bẹ́ẹ̀ yẹ láti ṣìpẹ̀ lótìítọ́ fún àwọn ọmọ Ọlọ́run?

Bí ó bá jẹ́ bẹ́ẹ̀, jẹ́ kí á gbé ohùn àdúrà ìṣìpẹ̀ sókè nísinsìnyí láti ṣìpẹ̀ fún irú àwọn ènìyàn wọ́nyí tí èṣù ti ṣètò láti pa ọkàn wọn run láti má jẹ̀ kí wọn jọba pẹ̀lú Krístì nípa mímú wọn yapa kúrò nínú ìfẹ́ àti ètò Ọlọ́run fún wọn nínú ìgbéyàwó wọn.

A gbọ́dọ̀ mọ̀ pé ìkọ̀sílẹ̀ jẹ́ àmì ìpadàbọ̀ Olúwa wa Jésù Krístì lẹ́ẹ̀kejì. Ó jẹ́ àmì



òpin ayé nítorí pé bíbélì sọ pé ní ìkẹhìn ọjọ́àwọn ẹlẹ́gàn yíò dé, wọn ó ma rìn nípa ìfẹ́ ara wọn. 2 Pet 3:3. Lọ́kọláya tí ó bá kọ ara wọn sílẹ̀ n rìn nínú ìfẹ́ ara wọn.

Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, nígbàtí ìjọ bá ri pé ẹnìkan nínú ìkọ̀sílẹ̀ ti dúró pẹ́, fún bóyá bí ọdún mẹ́wàá tàbí ogún ọdún tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ pàápàá nítorí ìyọnu àwọn ènìyàn, wọ́ n le gbà kí irú àwọn ẹni bẹ́ẹ̀ tí ó sì jọ́sìn pẹ̀lú àwọn ènìyàn mímọ́ tún ìgbéyàwó ṣe. Ó ṣe pàtàkì fún wa láti mọ̀ kí á sì gba otítọ́ ọ̀rọ̀ Ọlọ́run pé èyí kò tọ̀nà. Ẹnikẹ́ni nínú ìkọ̀sílẹ̀ kò lè tún ìgbéyàwó ṣe tí kò bá ti lè gbà ẹnití ó kọ̀ sílẹ̀ padà.

Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run nínú Gal 6:7 gbà wá nímọ̀ràn pé kí á má ṣe ṣì wá darí, àti pé a kò lè gan ìdájọ́ Ọlọ́run. Ohun tí a bá gbìn nìkan ni a le ká, ohunkóhun tí o bá sì ṣe ni ó ní èrè. Bí o bá gbìn láti tẹ́ ara rẹ lọ́rùn, o ó ká èso ìbànújẹ́ àti ibi.

Bákannáà, bí o bá gbìn láti wu Ọlọ́run, ìwọ yíò ká ayọ̀ àti ìyè ayérayé. Irú irúgbìn wo ni ò n gbìn?

Jẹ́ kí ìjọ mímọ́ mọ̀ pé, a nílò àwọn àdúrà ìṣìpẹ̀. Àwọn méjèèjì tí ọ̀rọ̀ náà kàn kò lè dá ṣe é nígbàmíràn. Àwọn kan ní láti fi àdúrà jagun fún wọn (Matt. 1:20-23). Jésù wá sáyé láti gbà wá nítorí pé a kò lè gba ara wa lọ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ àti èrè rẹ. Bó ti wù kí á dára tó, a kò lè mú ẹ̀dá ẹ̀ṣẹ̀ tí ó wà nínú wa kúrò. Jésù nìkan níi ó le ṣe èyí.



## ORÍ KẸTA

Kí ẹ kọ́ mọ èyí, pé kò sí ọ̀kan nínú àsọtẹ́lẹ̀ inú ìwé mímọ́ tí ó ní ìtumọ̀ ìkọ̀kọ̀. Nítorí àsọtẹ́lẹ̀ kan kò ti ipa ìfẹ́ ènìyàn wá rí; ṣùgbọ́n àwọn ènìyàn mímọ́ Ọlọ́run n sọ̀rọ̀ láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run bí a ti n darí wọn láti ọwọ́ Ẹ̀mí Mímọ́ wá." 2 Pet 1:20-21.

Ó ṣe pàtàkì fún ọ ní ìkọríta yìí láti mọ̀ pé ìpè nlá ni èyí jẹ́ sí ọ láti ọ̀dọ̀ Ẹlẹ́dàá rẹ láti mú ọ padà sọ́dọ̀ ara rẹ̀ nípa agbára àti ore-ọ̀fẹ́ Rẹ̀. Ó sì tún ṣe pàtàkì fún ọ láti mọ̀ pé ẹnikẹ́ni kò lè túmọ̀ ọ̀rọ̀ Ọlọ́run sí ti ara rẹ̀ bíkòṣe bí a ti fi fún un.

Ìwé yìí dá lé orí ìtọ́ni, ìdarí àtí ìmọ̀ràn Ẹ̀mí Mímọ́ láti tú ọkàn rẹ sílẹ̀ lọ́wọ́ ègbé

àti ìparún ayérayé, tí ọ̀ta ọkàn rẹ (èṣù) ti fi lélẹ̀ fún ọ. Mo gbàdúrà pé agbára nlá Ọlọ́run yíò tú ẹ̀mí, ọkàn àti ara rẹ sílẹ̀, yíò sì dá ọ nídè nísinsìnyí ní orúkọ nlá Jésù. Àmín. Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run sọ wípé bí Ọmọ Ọlọ́run bá sọ yín di òmìnira, ìwọ yíò di òmìnira nítòótọ́. Jòhánù 8:36.

O ní láti yàn kí o sì pinnu báyìí ẹnití ìwọ yíò tẹ̀lé. Èṣù - ẹlẹ́tàn rẹ, tí n sọ fún ọ wípé kíni ìdí ti o ó fi pa ara rẹ nítorí rẹ̀. Ẹni tí ó fi ẹ̀tàn fún ọ ní àwọn ìdí púpọ̀ tí o kò fi gbọdọ̀ bá ẹnìkejì tàbí Ọlọ́run rẹ làjà. Ẹni tí ó ṣẹ̀dá ìgbéyàwó láàrin ìwọ àti ẹnìkejì rẹ, Òun ni ó ti pè ọ́ láti wá sọ́ dọ̀ rẹ̀ fún àtúnto ayé àti ìgbéyàwó rẹ, kí èṣù má bà rẹ́ ọ jẹ ní ohun tí í ṣe tìrẹ ní ayé yìí àti ayé tí n bọ̀. Mo gbàdúrà wípé kí o gba ore-ọ̀fẹ́ láti yan Ẹlẹ́dàá rẹ àti láti jẹ́ ìpè Rẹ̀ ní orúkọ nlá Jésù, Àmín.

"Nítorí náà ẹ fi gbogbo èérí àti búburú àṣelékè lẹ̀lẹ̀ lí apá kan, kí ẹ sì fi ọkàn tútù gba ọ̀rọ̀ náà tí a gbìn, tí ó lè gba



ọkàn yín là. 22. Ṣùgbọ́n kí ẹ jẹ́ olùṣe ọ̀rọ̀ náà, kí ó má sì ṣe olùgbọ́ nìkan, kí ẹ máa tan ara yín jẹ. 23. Nítorí bí ẹnìkan bá jẹ́ olùgbọ́ ọ̀rọ̀ náà, tí kò sì jẹ́ olùṣe, òún dàbí ọkùnrin tí n ṣàkíyèsí ojú ara rẹ̀ nínú àwojiji: 24 Nítorí ó ṣàkíyèsí ara rẹ̀, ó sì bá tirẹ̀ lọ, lójúkan náà ó sì gbàgbé bí òún ti rí. 25. Ṣùgbọ́n ẹni tí ó bá n wo inú òfin pípé, òfin òmìnira nì, tí ó sì dúró nínú rẹ̀, tí òun kò jẹ́ olùgbọ́ tí n gbàgbé, bíkòṣe olùṣe iṣẹ́, olúwarẹ̀ yíò jẹ́ alábùkún nínú iṣẹ́ rẹ̀". Jákọ́bù 1:21-25.

Sí ọ, a kọ ìwé kékeré yìí; ní gbígbà ọ́ níyànjú àti jíjẹ́rìí sí ìpinnu àti ìfẹ́ Ọlọ́run fún ayé rẹ, Ó sì n fẹ́ kí o dúró níbẹ̀. 1Pet 5:12.

**JÀ FÚN AYỌ RẸ**

Èé ṣe tí ìwọ yíò gbá èṣù àti àwọn ọmọ ogun rẹ̀ láàyè láti jà ọ́ lólè ọ̀kan nínú àwọn ìgbádùn tí ó ṣààyò nínú ìgbàlà gẹ́gẹ́bí ọmọ Ọlọ́run? Lótìítọ́, o ti pinnu

láti má tùn ìgbéyàwó ṣe nítorí o gbàgbọ́ pé o lè mú ara dúró. Ó dára, ṣùgbọ́n èéṣe tí o kò kọjú ìjà sí ọ̀tá ni, tí ó fẹ́ jà ọ́ lólè ìdílé aláyọ̀. Máṣe gbà fún èṣù, ayannijẹ́ ni, máṣe káwọ́ gbera kí o sì jẹ́ kí ó jà ọ́ lólè ayọ̀ rẹ. Njẹ́ o mọ̀ pé bí o bá jọ̀wọ́ fun lórí ọ̀rọ̀ ìgbéyàwọ́ rẹ, òun yíò fi ọwọ́ kannáàn wọn apá ibòmíràn nínú ayé rẹ?

Ó yẹ kí o mọ̀ wípé bí o bá fún èṣù ní máìlì kan, ó ṣetán láti lọ ní máìlì mẹ́wàá. Nítorì náà, máṣe fún un ní ààyè kankan. Máṣe jọ̀wọ́ ara rẹ fún ìfẹ́ rẹ. Ìfẹ́ rẹ ni láti rí ìwọ àti ẹnìkejì rẹ ní ìyapa. Nígbàtí o ti mọ èyí, pinnu láti jà fún ìgbéyàwó rẹ kí o sì gba ẹnìkejì rẹ kúrò lọ́wọ́ èṣù. Olúwa tíí ṣe balógun lójú ìjà ayé wa kò fẹ́ ojo nítorí náà ni Ó ṣe dásí apá yìí nínú ayé rẹ. Èéṣe tí ìwọ parí rẹ̀ nínú iṣe rẹ wípé Òun (Ọlọ́run) kò tó? Nípa yíyan ìkọ̀sílẹ̀, ó n fihàn wípé Ó lè ṣe ohun gbogbo yàtọ̀ sí apa yìí nínú ayé rẹ, nípa bẹ́ẹ̀, o sọ Ọ́ di aláìpé. O kò tìí rí



ìyàtọ̀ nítorí o kò tíi ṣe ohun ní ọ̀nà tí ó tọ́. Bẹ́ẹ̀ni, o lè ṣe ohun gbogbo, ọ̀rọ̀ ìgbéyàwó rẹ kò sì yọ sílẹ̀, o kàn ní láti gbọ́ràn sí àṣẹ rẹ̀ ni; àní ohun gbogbo tí Ó n pa láṣẹ fún ọ nínú ìwé yìí. Ìwọ sá gbìyànjú rẹ̀, mo sì gbá Ọlọ́run gbọ́ láti wọ inú rẹ̀ pẹ̀lú rẹ fún ìṣẹ́gun ní orúkọ nlá Jésù, Àmín.

Ọlọ́run mọ bí Òun ó ti gba ẹni bí Ọlọ́run nínú ìdánwò àti ìṣẹwò ayé yìí; mo lè sọ fún ọ pé, òun yíò gbà ọ́ dájúdájú nígbà tí o bá ṣe ìfẹ́ àti àṣẹ rẹ̀. 2 Pet 2:9a.

**GBA Ọ̀RỌ̀ ỌLỌ́RUN**

Ó ṣe pàtàkì fún ọ láti gba ìjìnlẹ̀ ọ̀rọ̀ Ọlọ́run pẹ̀lú ọkàn tútù, èyí tí ó lè gba ọkàn rẹ là. Ṣe èyí tí Ẹlẹ́dàá rẹ n sọ fún ọ nísinsìnyí. Gbọ́ràn si títí dé òpin. Má ṣe jẹ́ olùgbọ́ ọ̀rọ̀ Rẹ̀ nìkan, bíkòṣe olùṣe ọ̀rọ̀ Rẹ̀. Kí o má ba tan ara rẹ nítòrí ó ṣòro fún ọ láti gan Ọlọ́run.

Gba ọ̀rọ̀ Rẹ̀, Òun ni ó kọ ọrọ Rẹ̀, Òun sì ni ó kọ́ ayé rẹ. Oun ni ó ṣètò ayé rẹ, Ó sì n sọ fún ọ lọ́wọ́ yìí wípé ìkọ̀sílẹ̀ kìí ṣe ohun láti yàn fún ìgbéyàwó rẹ. Mo rọ̀ ọ́ láti gbọ́ràn si lẹ́nu, kò lè sì ọ́ darí. Bíbélì wípé, Òun ni ìpilẹ̀ṣẹ̀ àti aláṣepé ìgbàgbọ́ wa - Jákọ́bù 1:21-22.

Níti òtítọ́, bíbélì sọ pé ní àárín àwọn ènìyàn Ọlọ́run, obìnrin kò lè wà láìsí ọkùnrin bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni ọkùnrin kò lè wà láìsí ọbìnrin. Èéṣe tí o fi jẹ́ kí èṣù tàn ọ́ ? Ó n rìn kiri, ó n bú ramúramù bìí kìnìún, ó n wá ẹni tí yíò pajẹ. Mo gbàdúrà pé o kò ní bọ́ sínú pàkúté èṣù ní orúkọ nlá Jésù. Àmín.

**BÁWO NI O ṢE GBỌ́N SÍ?**

O ti n gbé àwọn ìgbésẹ̀ nípa ìgbéyàwó rẹ nínú ọgbọ́n tìrẹ, tí o sì n kọ ọgbọ́n Ọlọ́run sílẹ̀. O tì wá ìmọ̀ lọ́dọ̀ àwọn ọ̀rẹ́ ayé yìí àti lọ́dọ̀ àwọn tí o pè ní ẹ̀bí onígbàgbọ́, ṣùgbọ́n tí ọkàn wọn kò sí ní mímọ́. Bíbélì sọ wípé nípa èso wọn ni a ó



fi mọ̀ wọ́n. Mo rọ̀ ọ́ kí o rìn ní ọ̀nà Ọlọ́run kí o sì tẹ̀lé ipasẹ̀ Rẹ̀.

Bí ìwọ̀ bá gbọ́n tí ọ̀nà Ọlọ́run sì yé ọ, ṣe àfihàn rẹ nípa gbígbé ìgbé ayé tí ó ní ọlá, ní ṣíṣe iṣẹ́ rere pẹ̀lú ìrẹ̀lẹ̀ tí ọgbọ́n n mú wá. Tí o bá n jowú kíkorò, tí àdánìkànjẹ sì wà nínú ọkàn rẹ, máṣe bo òtítọ́ mọ́lẹ̀ pẹ̀lú ìyangàn àti irọ́ pípa; nítorí owú jíjẹ àti àdánìkànjẹ kì í ṣe ọgbọ́n Ọlọ́run. Àwọn ohun bẹ́ẹ̀ jẹ́ ti ara àti ti ẹ̀mí èṣù. Nítorí níbikíbi tí owú jíjẹ àti àdánìkànjẹ bá wà, níbẹ̀ ni rùdurùdu àti ibi oríṣiríṣi yíò wà. Njẹ́ o mọ ẹnikẹ́ni tí ó wípé òún jẹ́ ọlọgbọ́n ṣùgbọ́n tí ó n hùwà òmùgọ̀/aṣiwèrè? Ìhùwàsí ènìyàn ni ó jẹ́ ìdiwọ̀n fún ọgbọ́n tóòtọ́; gẹ́gẹ́bí a ti le dá igi mọ̀ pẹ̀lú irú èso tí ó n so. O lè ṣe àyẹ̀wò ọgbọ́n rẹ pẹ̀lú àwọn ìhùwàsí àti ìgbésẹ̀ rẹ̀: ìwà wèrè n já sí rúdurùdu, ṣùgbọ́n ọgbọ́n a máa já sí àlàáfíà àtí ìṣerere. Jẹ́ ọlọgbọ́n kí o sì máa wá àlàáfíà èyí tí olùdásílẹ̀ ìgbéyàwó fi lélẹ̀ fún ọ nínú ìwé

yìí. O jẹ́ ìfẹ́ Ọlọ́run fún ọ láti jẹ́ ọlọgbọ́n nípa jíjẹ́ onílàjà. Jákọ́bù 3:13-18.

Ọgbọ́n tí à n retí láti ọ̀dọ̀ rẹ jẹ́ ọgbọ́n láti òkè wá, èyí tí bíbélì nínú ìwé Jákọ́bù 3:17 sọ wípé a kọ́kọ́ jẹ́ mímọ́, bẹ́ẹ̀ ló sì tún n fẹ́ àlàáfíà, ó sì wà ní pẹ̀lẹ́ ní gbogbo ìgbà, Ó ṣetán láti gbà fún àwọn elòmíràn. Ọgbọ́n tí Ọlọ́run nretí láti ọ̀dọ̀ rẹ jẹ́ èyí tí ó kún fún àánú àti ìṣe rere. Jákọ́bú 3:13-18.

## ÌRẸ̀LẸ̀

Ìwà ìrẹ̀lẹ̀ rẹ ṣe pàtàkì, nítorí nínú ìrẹ̀lẹ̀ rẹ ni Olúwa Ọlọ́run rẹ yíò ṣiṣẹ́ ore-ọ̀fẹ́ nínú ayé rẹ. O nílò ore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run lórí rẹ láti ṣe gbogbo àwọn nkan wọ̀nyí, ṣùgbọ́n pẹ̀lú ẹ̀mí ìrẹ̀lẹ̀ nìkan ni o le fi rìn nínú ore-ọ̀fẹ́ àtọ̀rùnwá yìí. Ó ṣe kókó fún ọ láti jọ̀wọ́ ara rẹ àti ìfẹ́ rẹ fún ìfẹ́ Ọlọ́run fún ayé rẹ ní àkókò yìí.

Ore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run wà fún ọ nígbàgbogbo láti rìn nínú rẹ. Bíbélì wípé Ọlọ́run kọjú



ìjà sí ìgbéraga, ṣùgbọ́n ó fi ore-ọ̀fẹ́ fún onírẹ̀lẹ̀.

Ìgbéraga máa n mú kí a mọ ti ara wa nìkan, ó sì n darí wa láti ṣe àkótán wípé gbogbo ohun tí a lè rí, fi ọwọ́ kàn tàbí rò lọ́kàn ni ó yẹ wá.

A lè túwasílẹ̀ lọ́wọ́ àwọn èrò ìmọtaraẹni nìkan wa nípa ríre ara wa sílẹ̀ níwájú Ọlọ́run, ní mímọ̀ wípé gbogbo ohun tí a nílò ni ìgbọ́ràn sí ọ̀rọ̀ rẹ̀. Jákọ́bù 4:6-7.

## GBÀDÚRÀ TÀBÍ SÌPẸ̀ FÚN ẸNÌKEJÌ RẸ/AGBÁRA ÀDÚRÀ

Ó ṣe pàtàkì fún ọ láti mọ̀ pé èsì àdúrà fún ẹnìkejì rẹ máa n lágbára ju bí o ti lérò pé ó ṣeéṣe lọ. Máṣe rí àdúrà gẹ́gẹ́bí ohun tí à n ṣe gbẹ̀hìn nígbàtí gbogbo ọgbọ́n ti pin. Àdúrà ni ó yẹ kí ó jẹ́ ilànà àkọ́kọ́, tí mò n dá bí àbá fún ọ láti gbìyàjú rẹ̀. Nígbàtí o bá ti gbìyànjú gbogbo èyí tí o mọ̀, gbogbo ọgbọ́n àti

ìmọ̀ràn, gbìyànjú àdúra, ìwọ yíò sì rí ìdáhùn sí ìbéèrè rẹ. Ogo ni fún Ọlọ́run wa lókè ọ̀run, ẹni tí n pè ọ́ nísinsìnyí nípa àánú Rẹ̀ láti wá sí ọdọ Rẹ̀ nínú àdúrà. Ó ṣetán láti fún ọ ni gbogbo ohun tí o bá béèrè, pẹ̀lú ẹ̀dùn ọkàn rẹ gbogbo. Mo gbàdúrà, kí o gba ore-ọ̀fẹ́ àti ìgboyà láti lọ sọ́dọ̀ Rẹ̀ nínú àdúrà báyìí, ní orúkọ nlá Jésù. Àmín. Jákọ́bù 5:13, 16b.

Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run nínú Jákọ́bù 5:16b wípé àdúrà olódodo nṣiṣẹ́ agbára, nítorí náà, gbàdúrà bàyìí lórí ọ̀rọ̀ náà ní pàtó, àbájáde àdúra rẹ yíò yà ọ́ lẹ́nu. Nínú ìjọba Krístì, gbogbo onígbàgbọ́ jẹ́ àlùfáà fún àwọn onígbàgbọ́ mìíràn. 1 Pet 2:9, ẹ̀yin ni olú-àlùfáà. Ìwọ jẹ́ àlùfáà fún ẹnìkejì rẹ. 1 Sam 12:23 wípé "pẹ̀lúpẹ̀lú bí ó ṣe ti èmi ni, kí á má ri pé èmí dẹ́ṣẹ̀ sí Olúwa ní dídẹ́kun àti gbàdúrà fun yín: èmí ó sì kọ yín ní ọ̀nà rere àti títọ́." Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ọmọ Ísráẹ̀lì ti ṣe ohun tó



burú lójú Ọlọ́run, òtítọ́ èyí tí ó sì hàn sí Sámúẹ́lì, síbẹ̀ ó pinnu, ó sì n fẹ́ láti gbàdúrà sí Ọlọ́run nítorí wọn.

Njẹ́ o mọ̀ wípé nípasẹ̀ àdúrà rẹ ni ìwọ yíò mú ẹnìkejì rẹ tí ó ti ṣáko lọ padà? Jákọ́bù 5:19-20 sọ wípé "Ará, bí ẹnikẹ́ni nínú yín bá sìnà kúrò nínú òtítọ́, tí ẹnìkan sì yíi padà; jẹ́ kí ó mọ̀ pé ẹnití ó bá yí ẹlẹ́ṣẹ̀ kan padà kúrò nínú ìṣìnà rẹ, yíò gba ọkàn kan là kúrò lọ́wọ́ ikú, yíọ́ sì bo ọ̀pọ̀lọpọ̀ èṣè mọ́lẹ̀."

Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run nínú ìwé Mat 5:44-48 pọn ní dandan fún wa láti fẹ́ àwọn ọ́tá wa. Olúwa pa láṣẹ fún wa láti gbàdúrà fún àwọn tí ó n ṣe inúnibíni sí wa. Nípa bẹ́ẹ̀, ìwọ yíò máa ṣe bí ọmọ Baba rẹ ní ọ̀run nítòótọ́, nítorí o fi oorun fún ẹni búburú àti ẹni rere, Ó sì rọ òjò sí orí olódodo àti aláìṣòdodo. Ẹlẹ́dàá rẹ sọ wípé, bí o bá fẹ́ àwọn tí ó fẹ́ ọ nìkan, èrè kínni ó wà níbẹ̀? Àwọn agbowó òde tí ó kún fún ìwà ìbàjẹ́ náà nṣe bẹ́ẹ̀. Bí o bá n ṣe rere tàbí tí ò n gbàdúrà fún àwọn ọ̀rẹ́ rẹ

nìkan, báwo ni o ṣe yàtọ̀ sí àwọn ẹlòmíràn? Ábèlèntàsé ẹnìkejì rẹ tí kìí ṣe bí àwọn ọ̀rẹ́ mìíràn. O ní láti jẹ́ pípé gẹ́gẹ́bí Krístì pẹ̀lú ti jẹ́ pípé.

Arákùnrin àti arábìnrin ọ̀wọ́n, bí ẹnìkan nínú yín bá ṣáko lọ kúrò nínú òtítọ́, tí a sì mú u padà nípa àdúrà ìṣìpẹ̀ àti ìṣe ìfẹ́ yín, ó dájú pé nígbàtí o bá mú ẹnìkejì rẹ padà (nípa ti ẹ̀mí àti ti ara), ìwọ yíò gbà á lọ́wọ́ ikú, yòó sì mú ìdáríjì ẹ̀ṣẹ̀ púpọ̀ wá. Jákọ́bù 5:19-20.

**ÒMÌNIRA RẸ: OHUN TÍ O YÀN**

A ti pè ọ́ sí òmìnira, bíbélì pọn ọ́n ní dandan fún wa pé "Nítorí a ti pè yín sí òmìnira, ará, kìkì pé kí ẹ má ṣe lo òmìnira yín fún ayé sípa ti ara, ṣùgbọ́n ẹ máa fi ìfẹ́ sin ọmọnìkejì yín." Gal 5:13. Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tọ́ka sí ìyàtọ̀ láàrin òmìnira sí ẹ̀ṣẹ̀ àti òmìnira láti sìn.

Òmìnira sí ẹ̀ṣẹ̀ kì í ṣe òmìnira rárá, nítorí pé ó n fìni sínú ìgbèkùn sàtánì, àwọn ohun mìíràn tàbí ẹ̀dá ẹ̀ṣẹ̀ ìwọ



tìkalára rẹ. O kò gbọdọ̀ jẹ́ ẹrú ẹ̀ṣẹ̀, nítorí pé o ní òmìnira láti ṣe ohun tí ó tọ́ àti láti fi ògo fún Ọlọ́run nípa iṣẹ́ ìsìn ìfẹ́ sí àwọn ẹlòmíràn, pàápàá sí ẹnìkejì rẹ.

Yàn láti fẹ́ràn ẹnìkejì rẹ, yàn láti ṣètọ́jú rẹ̀. Nígbàtí àwa onígbàgbọ́ bá ti sọ ìfẹ́ nù, a ó wa bẹ̀rẹ̀ sí máa wá àléébù àwọn ẹlòmíràn, a kì yíò sì rí ohun dídára nínú wọn mọ́, bíkòṣe ẹ̀bi wọn. Láìpẹ́ jọjọ, a ó sì tún sọ ìrẹ́pọ̀ wa nù. Èyí sì ni ìdí tí ó fi jẹ́ pé ohun tí ò n rí nínú ẹnìkejì rẹ jẹ́ ohun òdì; o kì í rí ohun dídárá kankan nínú rẹ̀, nítorí pé o ti kọ òfin ìfẹ́ Ọlọ́run sílẹ̀. Mo gbàdúrà pé Olúwa yíò fún ọ ní ore-ọ̀fẹ́ láti tún ìgbésẹ̀ rẹ gbé ní orúkọ nlá Jésù Krístì. Àmín.

**MÚ TÌRẸ NÍNÚ OHUN TÍ A KÀ SÍLẸ̀**

Èwo tàbí mélòó nínú àwọn iṣẹ́ tí a kà sílẹ̀ nínú ìwé Gal 5:20-21 ní a le pè mọ́ ọ? Jẹ́ olótìítọ́, kí o sì dẹ́kun àti máa tan ara rẹ. Ó dámilójú wípé ìwọ nìkan ni ò n ka

ìwé yìí. Olúwa tí ó mọ̀ ọ́ tí ó sì rí ọkàn rẹ wà pẹ̀lú rẹ nínú kíka ìwé yìí.

Èwo nínú àwọn ìwà yìí ni ó wà nínú ayé rẹ, nígbàtí gbogbo ènìyàn tilẹ̀ mọ̀ pé ọmọ Ọlọ́run ni ọ́? Èwo nínú wọn? Mélòó ni? Ṣé ìjà, inú bíbí, ìmọtara-ẹninìkan, ìpínyà, ìfẹ́kúfẹ̀ẹ́ ara, àgbèrè, àìmọ́, ìbọ̀rìṣà, ònrorò, owú jíjẹ, àìní ìrẹ́pọ̀, owú kíkorò, ìmutípara, ìréde òru àti àwọn ẹ̀ṣẹ̀ bí èyí ni a lè rí nínú rẹ. Dá ara rẹ àti Ẹlẹ́dàá rẹ lóhùn. Sá fún gbogbo rẹ, sá! Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run sọ wípé ẹnikẹ́ni tí ó ba n gbé irú ayé bẹ́ẹ̀ kì yíò jogún ìjọba Ọlọ́run.

Gbogbo wa la ní àwọn èrò ibi èyí tí a kò lè patì. Kí á ba lè tẹ̀lé ìtọ́ni Ẹ̀mí Mímọ́, a gbọ́dọ̀ pinnu láti kojú wọn. Àwọn èrò wọ̀nyí jẹ́ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ àfojúrí; bí àpẹẹrẹ, ònrorò, owú jíjẹ àti ìmọtaraẹni nìkan. Àwọn ẹni tí ó bá pa àwọn ẹ̀ṣẹ̀ yìí tì tàbí tí wọ́n kọ̀ láti kojú wọn, kò gba ẹ̀bùn ẹ̀mí



tí ó n jásí ìgbé ayé titun. Ó yẹ kí o mọ̀ bẹ́ẹ̀.

**Ìbínú**

Èyí kìí ṣe ohun tí a kọ́ lára Krístì Jésù, nítorí ìbínú máa n fi ẹsẹ̀ èṣù múlẹ̀ nínú ayé ènìyàn ni. Láìsí àníàní, ohun yìí ni èṣù n fẹ́ láti ṣe nínú ayé rẹ, láti lè mú ọ ní ìgbèkùn: ọjọ́ ọ̀la rẹ àti òpin iré-ìje rẹ tíí ṣe àti dé ọ̀run. Báwo lo ṣe dá ọ lójú sí pé opin iré-ìje rẹ yìí, èṣù ọtá rẹ kò tíì ja gbà mọ́ ọ lọ́wọ́, kìkì nípa arékérekè rẹ̀ láti mú ọ bínú kí o sì sọ ìfẹ́ rẹ fún ẹnìkejì rẹ nù.

Àbí o ti sọ ìfẹ́ rẹ fún ẹnìkejì rẹ nù? Hun!! Yípadà kí o sì padà wá sọ́dọ̀ Olúwa Jésù Krístì, kí o sì gba ẹnìkejì rẹ padà nípa ti ẹ̀mí àti ara. Mo gbàdúrà pé Olúwa yíò ràn ọ́ lọ́wọ́ ní orúkọ nlá Jésù. Àmín.

**ÌBÁLÀJÀ - OHUN ÀÌGBỌDỌ̀MÁṢE**

Ṣe ìlàjà láti mú ẹnìkejì rẹ padà sọ́dọ̀ rẹ àti Ọlọ́run. Ó ṣeéṣe kí ọkọ tàbí aya tìrẹ

sì máa gbé lábẹ́ òrùlé kan pẹ̀lú rẹ, ṣùgbọ́n ẹ kò gbé bíi tọkọtaya mọ́. Kò sí ìṣọ̀kan ti ọkàn àti èròngbà láàrin ẹ̀yin méjèèjì. O ní láti bá a làjà láti mu padà sọ́dọ̀ rẹ. Ìlàjà yìí kìí kàn ṣe ohun tí o nílò, bíkòṣe ohun àìgbọdọ̀máṣe.

Bí o bá jẹ́ aṣojú Krístì tòótọ́, wàyí ò, ìlàjà jẹ́ ohun àìgbọdọ̀máṣe fún ọ. Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run nínú 2 Kor 5:18-21; Ọlọ́run bá wa làjà nípasẹ̀ Jésù Krístì, Ó sì ti fún wa ní ìránṣẹ́ ìlàjà. Ọlọ́run bá gbogbo àgbáyé làjà sí ọdọ Òun tikalára Rẹ̀, láì ka ẹ̀ṣẹ̀ wọn sí wọn lọ́rùn. Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́, Ó n fẹ́ kí o bá ẹnikeji rẹ làjà padà sí ọ̀dọ̀ ìwọ tìkara rẹ, ní gbogbo ọ̀nà ayé rẹ, ní àìka ẹ̀ṣẹ̀ rẹ sí i lọ́rùn.

Nítorí, nígbàtí àwá jẹ́ ọ̀tá Ọlọ́run, a ṣe ìlàjà wá sí ọ̀dọ̀ Òun nípasẹ̀ ẹ̀jẹ̀ ọmọ Rẹ̀, dájúdájú àwa yíò sì rí ìgbàlà nípasẹ̀ ẹ̀mí ọmọ Rẹ̀. Kol 1:20-23, Ọlọ́run ṣètò àláàfíà pẹ̀lú ohun gbogbo ní ọ̀run àti ní



ayé, àti ìwọ pẹ̀lú, ẹnití ó ti jìnà sí i nígbà kan rí. Ọ̀tá rẹ̀ ni ìwọ́ jẹ́, tí o sì ti yapa kúrò lọ́dọ̀ Rẹ̀ nípa èrò àti iṣẹ́ búburú rẹ, síbẹ̀ òun bá ọ làjà nípa ikú Krístì nínú ara. Ní àtàrí èyí, Òún ti mú ọ wá sí iwájú Rẹ̀, ìwọ́ sì ti di mímọ́ àti aláìlábàwọ́n bí o ti dúró níwájú Rẹ̀, láìsí ẹ̀bi kan. Ṣùgbọ́n o gbọ́dọ̀ tẹ̀síwájú ní gbígba òtítọ́ yìí gbọ́ kí o sì dúró ṣinṣin nínú rẹ̀. Èéṣe tí ìwọ ò ṣe dìde fún ìgbàlà àti ìtúsílẹ̀ ẹnikeji rẹ lọ́wọ́ ìparun yìí, kódà bí o bá tilẹ̀ gbàgbọ́ wípé ò n gbé inú ẹ̀ṣẹ̀.

Njẹ́ o mọ̀ wípé oríkunkun rẹ láti fi í sílẹ̀ nínú ẹ̀ṣẹ̀ yíò ti ìwọ náà sínú ẹ̀ṣẹ̀.? Nítorí náà, èéṣe tí o kò bá ẹnikeji rẹ làjà ní gbogbo èyà ìgbéyàwó rẹ. O lè jẹ́ ẹni tí a kọ̀ sílẹ̀ díẹ̀ tàbí ẹni tí a kọ̀ sílẹ̀ pátápátá gẹ́gẹ́bí wọ́n ti máa n sọ. Ìpè tí à n pè ọ́ báyìí jẹ́ ti ìlàjà nítorí nínú sùúrù rẹ ni ìwọ yíò gba ọkàn rẹ padà. Lúkù 21:19.

Ní sùúrù, máșe kúrò nínú ìdàpọ̀ rẹ: șe sùúrù, máșe jáde kúró nínú ìfẹ́ Ọlọ́run fún ayé rẹ; kí o má baà pàdánù ọkàn rẹ. Mo gbàdúrà wípé o kò ní pàdánù ọkàn rẹ ní orúkọ nlá Jésù. Àmín. Kàásí wípé ìpamọ́ra Olúwa wa sí ìgbàlà ni. Olúwa wa fún ọ ní ààyè láti rí ìgbàlà. 2 Pet 3:15.

Olùfẹ́, máșe jẹ́ kí àwọn àpẹẹrẹ búburú yìí kí ó yí ọ padà, tẹ̀lé kìkì ohun tí ó dárá. Șèràntí pé àwọn tí ó n șe rere n fihàn pé ọmọ Ọlọ́run ni àwọn í șe bẹ́ẹ̀ pẹ̀lú, àwọn tí n șe búburú n fihàn gbangba-gbàngbà pé àwọn kò mọ Ọlọ́run. Ìkọ̀sílẹ̀ jẹ́ ohun búburú ní ojú Ọlọ́run, nítorí ó jẹ́ ẹrú ẹ̀ṣẹ̀ yálà láti ara ìkóríìrà, àìní ìdáríjì tàbí ọ̀pọ̀ ohun mìírán. Bíbélì sọ nínú ìwé Gal 5:21d wípé irú àwọn ẹni bẹ́ẹ̀ kì yíò wọ ìjọba Ọlọ́run. Mo gbàdúrà pé o kì yíò kùnà àti dé ọ̀run ní orúkọ nlá Jésù. Àmín.



ORÍ KẸRIN

## ÈRÒ ÌPARÍ/ÀKÓTÁN

Ó hàn gbangba pé ọ̀rọ̀ Ọlọ́run jẹ́ òtítọ́, àti pé a gbọ́dọ̀ gba ọ̀rọ̀ Ọlọ́run yìí fún wa láti jọba pẹ̀lú Rẹ̀. A ní láti fi ayọ̀ gba ọ̀rọ̀ Rẹ̀: o kò mọ Ọlọ́run tí o kò bá pa òfin rẹ̀ mọ́. 1Johánù 2:3-4.

Ayọ̀ nlá mbẹ níwájú, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé o ní láti farada àwọn ìdánwò fún ìgbà díẹ̀. Ìdánwò wọ̀nyí ni yíò fihàn pé ojúlówó ni ìgbàgbọ́ rẹ. À n dán ọ wò gẹ́gẹ́ bí àti n fi iná sọ wúrà di mímọ́, bí ó ti jẹ́ pé ìgbàgbọ́ rẹ șe iyebíye ju wúrà lọ. Nítorí, nígbàtí ìgbàgbọ́ rẹ bá dúró șinșin nínú àwọn ìdánwo, yíò mú ìyìn, ògo àti ọlá wá fún ọ ní ọjọ́ tí a bá fi Jésù Krístì hàn fún gbogbo ayé. 1 Pet 1:6-7.

Rántí pé, ó dára láti jìyà fún ṣiṣe rere, nítorí èyí ni oun tí Ọlọ́run n fẹ́, ju pé kí á jìyà fún ṣíṣe búburú. Krístì jìyà fún ẹ̀ṣẹ̀ wa lẹ́ẹ̀kan ṣoṣo: Kò dẹ́ṣẹ̀ rí, ṣùgbọ́n ó kú fún ẹlẹ́ṣẹ̀ láti mú ọ wá sílé sọ́dọ̀ Ọlọ́run. Ó jìyà ikú ti ara, ṣùgbọ́n, a jí i dìde sí ìyè.

Tí o bá kórìírà ẹnìkejì rẹ fún ìdí kídìí, o wà nínú òkùnkùn. Nítorí náà, ẹni tí èṣù ni ọ́. Jésù gbé ìgbé ayé ti òtítọ̀ àṣẹ yìí, ìwọ pẹ̀lú sì ní láti gbé ìgbé ayé bẹ́ẹ̀. Tí o bá sọ wípé ò n gbé nínú ìmọ́lẹ̀, ṣùgbọ́n tí o kórìírà arákùnrin tàbí arábìnrin rẹ kí á má tíì sọ pé ẹ̀yà ara rẹ, ẹnìkejì rẹ, ò n gbé nínú òkùnkùn. 1 Jòhánù 2:8-9. Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run sọ nínú 1Jòhánù 2:3-4 wípé kìkì nípa pípa òfin rẹ̀ mọ́ ni o fi lè mọ̀ Ọ́.

Ọlá nlá ni a ó fi fún ọ nígbàtí o bá farada ìjìyà. Bí àpẹẹrẹ, ó mọ̀ nípa Jobu: ọkùnrin tí ó ní ìfaradà nlá, ìwọ́ lè fi bí



Olúwa ti ṣe dára si ní ìkẹyìn; Olúwa kún fún ìṣoore àti àánú. Nínú ìpọ́njú òun ìjìyà rẹ tàbí ètò ìkọ̀sílẹ̀ nípa ti ẹ̀mí àti ti ara, ó yẹ kí o gbàdúrà - Jákọ́bù 5:11, 13.

Nítorí náà, ẹ̀yin ará mi ọ̀wọ́n lọ́kùnrin àti lóbìnrin, ẹ ṣiṣẹ́, ẹ ṣiṣẹ́ kárakára láti fihàn pé ẹ wà lára àwọn tí Ọlọ́run ti pè tí ó sì yàn. Ẹ ṣe àwọn ohun wọ̀nyí, ẹ̀yin kì yíò sì bọ́ sọnù. Ọlọ́run yíò sì gbà yín wọlé sínú ìjọba ayérayé ti Olúwa àti Olùgbàlà wa Jésù Krístì pẹ̀lú ọlánlá. Àmín. 2 Pet 1:10-11.

2 Pet 3:8-9 "Ṣùgbọ́n, olùfẹ, ẹ máṣe gbàgbé ohun kan yìí, pé ọjọ kan lọ́dọ̀ Olúwa bí ẹgbẹ̀rún ọdún ni ó rí, àti ẹgbẹ̀rún ọdún bí ọjọ́ kan. Olúwa kò fi ìlérí Rẹ̀ jáfara, bí àwọn ẹlòmíràn ò ti ka ìjáfara sí, ṣùgbọ́n Ó n mú sùúrù fún nítorí kò fẹ́ kí ẹnikẹ́ni kí ó ṣègbé, bíkòṣe

kí gbogbo èniyàn kí ó wá sí ìrònúpìwàdà." Ó ṣe pàtàkì pé kí ó máṣe gbàgbé ohun kan yìí ọ̀rẹ́ mi ọ̀wọ́n, ọjọ́ kan bí ẹgbẹ̀rún ọdún ni sí Ọlọ́run àti ẹgbẹ̀rún ọdún bí ọjọ́ kan. Olúwa kò lọ́ra nípa àwọn ìlérí Rẹ̀ bí àwọn kan ti rò. Rárá! Ó n ṣe sùúrù nítorí tìrẹ ni. Òun kò fẹ́ kí ẹnikẹ́ni kí ó ṣègbé ṣùgbọ́n Ó fẹ́ kí gbogbo èniyàn ronúpìwàdà. "Ìrònúpìwàdà sí ìlàjà", ìlàjà pẹ̀lú ẹnìkejì rẹ ní gbogbo ọ̀nà ayé yín, ìbáàjẹ́ ní ti ẹ̀mí tàbí ti ara. Mo gbàdúrà pé Olúwa Ọlọ́run alágbára yíò ràn ọ́ lọ́wọ́ ní orúkọ nlá Jésù. Àmín.

## ÌSINMI TÍ A ṢÈLERÍ FÚN ÀWỌN ÈNÌYÀN ỌLỌ́RUN

Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run ti fi dá wa lójú pé ìsinm wà, a sì gba ọ̀rọ̀ Rẹ̀ gbọ́, nítorí Ẹ̀mí Mímọ́ n ṣe ẹlẹ́rìí òtítọ́ Rẹ̀ nínú wa. Ìlérí Ọlọ́run láti wọ inú ìsinmi Rẹ̀ dúró, nítorí náà, ó yẹ kí á bẹ̀rù wípé àwọn kan nínú wa lè kùnà láti ní ìrírí Rẹ̀. Nítorí ìhìnrere yìí tí



Ọlọ́run ti pèsè, a ti kéde ìsinmi yìí fún wa gẹ́gẹ́bí ó ti ṣe wà fún wọn. Ṣùgbọ́n kò ṣe wọ́n ní rere, nítorípé wọn kò pín nínú ìgbàgbọ́ àwọn tí ó gbọ́ ti Ọlọ́run. Nítorí náà, ìsinmi Ọlọ́run wà níbẹ̀ fún àwọn èniyàn láti wọ inú rẹ, ṣùgbọ́n àwọn tí ó kọ́kọ́ gbọ́ ìhìnrere yìí kùnà láti wọ inú rẹ̀ nitorí tí wọ́n ṣe àìgbọràn sí Ọlọ́run. Lónìí, bí o bá ti gbọ́ ohùn rẹ̀, máṣe sé ọkàn rẹ le. Ẹ jẹ́ kí á sa ipá wa láti wọ inú ìsinmi náà. Ṣùgbọ́n bí a bá ṣe àìgbọràn sí Ọlọ́run bí àwọn ará Ìsráẹ́lì ti ṣe, àwa náà yíò kùnà. Heb. 4:1, 11.

Ará, mo gbàdúrà wípé o kì yíò kùnà ní orúkọ Jésù, Àmín. Ó ṣe pàtàkì pé kí o gbé ayé rẹ ní ìbámu pẹ̀lú ìfẹ́ Ọlọ́run fún ayé rẹ, kí o sì fi àgbékalẹ̀ bíbélì ṣe olùdarí rẹ nípa agbára Ẹ̀mí Mímọ́. A ó dé ìjọba ọ̀run ní orúkọ Jésù Krístì, Àmín.

Ronú sí èyí pé, bí a bá fi agbára kaká gba olódodo là, níbo ni aláìwàbí Ọlọ́run

àti ẹlẹ́ṣẹ̀ yíò já sí? Èyí ni wípé, bí Olúwa kò bá fi ọwọ́ sí ìkọ̀sílẹ̀ nínú ilànà rẹ̀, níbo ni ìdúró rẹ yíò wà pẹ̀lú ní Páràdísè? Tún èrò rẹ pa arákùnrin, tún èrò rẹ pa arábìnrin. 1 Pet 4:18.

## ADÉ ÒGO

> "Àti nígbàtí olórí olùṣọ́àgùntàn yíò bá sì fi ara hàn, ẹyin yíò gba adé ògo tí kì í ṣá", 1 Pet 5:4.

Èrè nlá n dúró dè ọ́ fún gbígbọ́ràn sí ọ̀rọ̀ àti òfin Rẹ̀; gbígbé inú àṣẹ rẹ̀ nínú gbogbo ẹ̀yà ayé rẹ.

Nítorí náà, ọ̀rẹ́ mi ọ̀wọ́n, bí o bá lérò wípé o dúró digbí, kíyesára, kí o má ba à subú. Ìdánwo inú ayé rẹ kò yàtọ̀ sí èyí tí àwọn ẹlòmíràn ní ìrírí rẹ̀. Olódodo sì ní Ọlọ́run, Òun kì yíò jẹ́ kí ìdánwò rẹ ju èyí tí o lè gbé lọ. Nígbàtí a bá dán ọ wò, Òun yíò fi ọ̀nà àbáyọ hàn ọ́. 1 Kor 10:12-13.

Kí ẹ sì ma kà á sí pé, sùúrù Olúwa wa ìgbàlà ni;" 2 Pet 3:15a.